# ABRAHAMU JẸ́ APẸẸRẸ IDALARE NIPA IGBAGBỌ́

**Romu 4:1-25; Gẹnẹsisi 12:1-3; 15:4-6**

**ẸkỌ 383 – FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ọkàn li a fi igbagbọ́ si ododo; ẹnu li a si fi ijẹwọ si igbala" (Romu 10:10).**

**I. Ododo nipa Igbagbọ́**

1. Abrahamu ri ododo gba nipa igbagbọ, ki i ṣe nipa iṣẹ, Romu 4:1-3; Gẹnẹsisi 15:6; Galatia 3:6; Jakọbu 2:23.
2. Bi igbala ba ti ipasẹ iṣẹ wá, i ba jẹ́ igbese ti Ọlọrun jẹ wa, ki i tun ṣe ore-ọfẹ mọ́, Romu 4:5; 11:6.
3. Dafidi jẹri si ẹkọ yii kan naa, Romu 4:6-8; Orin Dafidi 32:1, 2

**II. Ibukun Igbagbọ fun Awọn Akọla ati Awọn Alaikọla**

1. A dá Abrahamu lare nipa igbagbọ́ ṣaaju ikọla rẹ̀ ki oun ki o le jẹ baba gbogbo awọn ti o gbagbọ́, Romu 4:9-12; Galatia 3:7
2. A ṣe ileri fun Abrahamu nipa ododo ti igbagbọ, ki i ṣe nipa Ofin, Romu 4:13-17; Gẹnẹsisi 12:1-3; Galatia 3:18, 29

**III. Apejuwe Igbagbọ Abrahamu**

1. Ki a wi bi ẹda, o ṣoro fun Abrahamu lati ni ọmọkunrin, ṣugbọn o gba Ọlọrun ti O fi ofin ẹda lẹlẹ gbọ lati pe O le pa ofin ẹda ti sapakan lati mu ifẹ Rẹ̀ rẹ ẹ̀, Romu 4:18-22; Gẹnẹsisi 15:4-6; Heberu 11:11, 12
2. A kọ akọsilẹ yii fun igbala wa, ki awa ki o le gba Kristi gbọ́, ẹni ti O kú fun ẹṣẹ wa ti A si ji dide fun idalare wa, Romu 4:23-25; 2 Kọrinti 5:21; Galatia 1:4; 1 Peteru 1:21

**ALAYE**

**Ohùn Ọlọrun**

Abrahamu wa lati ilẹ Keferi nibi ti okunkun gbe bo ilẹ. O ṣe e ṣe ki awọn eniyan ibẹ dabi awọn wọnni ti Paulu ṣe apejuwe rẹ̀ ninu Romu 1:21-32. Wọn ko fẹ ni Ọlọrun ninu ironu wọn, nitori naa Ọlọrun fi wọn silẹ ninu iwa eeri gbogbo. Ṣugbọn laaarin ẹ̀ṣẹ ati okunkun ti o bo aye mọlẹ, ọkunrin kan wà ti Ọlọrun le fi ara Rẹ̀ hàn fun, ti o si le jẹ́ ipe Ọlọrun; Abraham ni ọkunrin naa.

O ya ni lẹnu pe ninu ayé ẹ̀ṣẹ ati okunkun, Ọlọrun le sọrọ ki iwọ si mọ pe ohun Ọlọrun ni. Ki i ṣe igba gbogbo ni ohùn Ọlọrun n wá ninu sisan aara gẹgẹ bi ti Oke Sinai tabi ni ohun jẹjẹ gẹgẹ bi ti Oke Horebu, ṣugbọn nigba ti O ba sọrọ, iwọ yoo mọ̀ ọn.

Ni ilẹ Keferi ti o ṣokunkun ni Abrahamu mọ ohun Ọlọrun, o si gba Ọlọrun gbọ. Igbagbọ ni mu ododo wọ inu ookan aya rẹ̀. Wo bi o ti ni lati rọrun to lati gbagbọ́ nigba ti a ba tọ eniyan dagba ni ilẹ Ihinrere nibi ti a ki i ti kọ́ ni lati foribalẹ fun oriṣa ti igi ati ti okuta! Ṣugbọn eṣu mu ẹkọ aigbagbọ tọ Efa wá inu Ọgba Edẹni. Yoo tilẹ gbiyanju lati mu un tọ ọ wa ani ninu ile Ọlọrun; ṣugbọn ranti pe Abrahamu gba Ọlọrun gbọ nigba ti aigbagbọ ati ibọriṣa yi i ká.

**Baba Gbogbo Awọn ti o Gbagbọ́**

Lẹẹkan ri Abrahamu jẹ abọriṣa, ṣugbọn Ọlọrun darijii, O si mu oun ati iru-ọmọ rẹ̀ lẹyin rẹ̀ wá sinu akanṣe majẹmu nipa eyi ti iru-ọmọ rẹ̀ yoo di ajogun ayé. A dá Abrahamu lare ni ọna kan ṣoṣo nipa eyi ti a le gbà dá ẹlẹṣẹ lare: nipa aanu Ọlọrun ati igbagbọ ati igbọran. Nipa igbagbọ o di olori tabi baba gbogbo awọn ti o gbagbọ́. Nigba ayé awọn baba nla (Patriaki), ohun nlá nlà ni lati jẹ baba, ati ju bẹẹ pẹlu lati jẹ baba odindi ẹya kan; o si jẹ ohun ti o tobi jù lọ ninu awọn ohun nla nla lati jẹ baba orilẹ-ede pupọ.

Pe a n da awọn olododo lare nipa igbagbọ han gbangba ninu igbesi-aye Abrahamu. O gba Ọlọrun gbọ a si ka a si ododo fun un. Fun igba pipẹ ṣaaju ki Oluwa to fi edidi di Majẹmu ti O ba Abrahamu ati iru-ọmọ rẹ̀ da nipa edidi ikọla, a ti da Abrahamu lare nipa igbagbọ. A ko sọ fun wa nipa bawo tabi igba ti Abrahamu kọ gba Ọlọrun gbọ; ṣugbọn Ọlọrun pe e, oun si jẹ ipe naa. Ki i ṣe kiki igbọran si ipe ti a pe e ni o fun Abrahamu idalare ṣugbọn igbagbọ ni o mu ki o ri ojurere

Ọlọrun. Iṣẹ rere a maa tẹle iṣọkan ọkan wa pẹlu Ọlọrun nipa igbagbọ. Jakọbu wi pe: "Fi igbagbọ́ rẹ hàn mi li aisi iṣẹ, emi o si fi igbagbọ́ mi hàn ọ nipa iṣẹ mi." Awọn Ju kan wa ni ilẹ Romu ti wọn n wi pe a gbọdọ kọkọ kọ ni ni ila ki a to le wa ni irẹpọ pẹlu Ọlọrun.

Wọn gbidanwo lati mu Ẹsin Kristi pada sabẹ Ofin. Paulu wi pe a ko le wa labẹ Ofin Mose ati abẹ oore-ọfẹ nipa Jesu Kristi lẹsẹ kan naa. Bakan naa ni iwọ ko le pa iṣe pọ mọ idalare. Bi iṣẹ ba so wa pọ pẹlu Ọlọrun, a jẹ pe ti igbese ni nigba naa, ki i si ṣe ti aanu ni a fi gba wa la. Ṣugbọn aanu Ọlọrun ni o gba wa la, ki i ṣe iṣẹ. (Ka Galatia 2:16; 3:11).

Meloomeloo awọn ẹlẹṣẹ ti ko ni iṣẹ rere kan lati fi tu Ọlọrun loju ni o ti ri oore-ọfe idariji gbà nigba ti wọn kunlẹ lori eekun wọn ti wọn si bẹbẹ fun aanu. Wọn gba ileri nì gbọ́, Ọmọ Ọlọrun si gbà wọn.

Dafidi wi pe: "Ibukún ni fun awọn ti a dari irekọja wọn jì, ti a bò ẹ̀ṣẹ wọn mọlẹ."

**Igbagbọ Tootọ**

Awọn miiran wà ti n jẹwọ igbagbọ ninu Jesu Kristi ṣugbọn ti wọn ro pe jijẹ ọmọ-ijọ wọn, iṣẹ aanu wọn, iṣẹ wọn ti wọn n ṣe yoo gbé wọn de Ọrun. Ṣugbọn Jesu wi pe, "A kò le ṣe alaitún nyin bi" (Johannu 3:7). Wọn gbojufo iriri atunbi, ṣugbọn wọn kan fi ọgbọn ori gba itan Jesu gbọ́.

Bibeli wi pe; Nitori ọkàn li a fi igbagbọ́ si ododo; ẹnu li a si fi ijẹwọ si igbala" (Romu 10:10). Wọn jẹ afọju ti a n ti ọwọ afọju fi ọna hàn, "Awọn mejeji ni yio si ṣubu sinu iho."

Awọn ẹlẹṣẹ ti o mọ ara wọn ni alailagbara ti wọn si bẹ Ọlọrun fun aanu n ri idariji gbà. Nipa igbagbọ ni wọn n ri idariji gbà ati iwẹnumọ wọn kuro ninu ẹ̀ṣẹ gbogbo. "Nitori igbati awa jẹ alailera li akokò ti o yẹ, Kristi kú fun awa alaiwa-bi-Ọlọrun" (Romu 5:6).

Bi iku Jesu ti jẹ etutu fun ẹṣẹ wa, bẹẹ gẹgẹ ni ajinde rẹ̀ jẹ ami ati ẹri fun iye ainipẹkun wa.

**Iru-ọmọ Abrahamu**

Ọdun n yi lu ọdun. Oluwa si mu Abrahamu jade ni oru ọjọ kan labẹ Ọrun ti o dabi ibori, o si dabi ẹni pe O n wi pe, "Abrahamu woke! Ka awọn irawọ! Bẹẹ ni iru-ọmọ rẹ yoo ri. Iwọ ri bi awọn iyanrin wọnyii ti pọ to? Iwọ ha le ka wọn bi? Nigba naa ni iwọ yoo le ka iru-ọmọ rẹ."

Abrahamu kò ni ọmọ, oun ati Sara aya rẹ̀ si ti di arugbo. Bi a ba fi oju ẹda wo o, kò si ireti ati bi ọmọ fun wọn mọ́. Ṣugbọn Abrahamu kò fi aigbagbọ ṣiyemeji ileri Ọlọrun. Fi ẹni kan ti o ni gbagbọ ninu iṣe ẹda hàn mi ẹni ti ko ri kọja igi imu rẹ̀ nipa ti ẹda. Abrahamu ko si ni isọwọ iru awọn eniyan bẹẹ. Oun ko ṣiyemeji, ireti rẹ̀ duro ṣinṣin. Nipa igbagbọ ti o duro gangan, ti kò mi sihin tabi sọhun, o di baba igbagbọ́. Awa ti a gbagbọ ni ọmọ Abrahamu. Awọn Ju n fẹ sọ pe awọn nikan ni ọmọ Abrahamu. Paulu wi pe ki iṣe eyi ti o fara hàn ni Ju ṣugbọn Ju ti inu ni Ju. O wi pe a fi ileri yii fun Abrahamu nigba ti oun jẹ Keferi, ati pe ileri yii jẹ ti Iru-ọmọ rẹ̀ ti o jẹ ọ̀kan, ani Kristi. Bi a ba ti sọ wa di ẹbi Ọlọrun nipa ibi titun, awa jẹ iru-ọmọ Kristi ati irandiran Abrahamu.

Ibi Isaaki jẹ́ iyanu. Ibi Kristi jẹ́ iyanu. "Ibi titun," jẹ́ iyanu. Abrahamu ko mọ bi Ọlọrun yoo ṣe sọ iru-ọmọ rẹ̀ dabi iyanrin okun, ti a ko le kà, ṣugbọn o mọ pe ko si ohun ti o ṣoro fun Ọlọrun. Awọn Onigbagbọ ni awọn wọnni ti o gbagbọ gẹgẹ bi ti Abrahamu. Wọn jẹ iru-ọmọ rẹ̀ nipa ti ẹmi. Ileri igbala wà fun awọn ti o gba Kristi gbọ́, nitori Oun ni iru-ọmọ ti a ṣeleri.

## AWỌN IBEERE

1. Bawo ni Abrahamu ṣe ri idalare gbà? Bawo ni awa ṣe n ri idalare gbà?
2. Ki ni ṣe ti a fi n pe Abrahamu ni baba awọn ti o gbagbọ́?
3. Sọ ọna ti awọn Keferi gba jẹ alabapin ileri ti a ṣe fun Abrahamu?
4. Njẹ ileri ti a ṣe fun Abrahamu wá nipa Ofin?
5. Iwe Mimọ wi pe Abrahamu jọ́ alagbara nipa igbagbọ. Darukọ awọn ohun ti o jẹ ki a pe e bẹẹ.